**AKIYESI**

Anfẹ aṣoju ni awọn ilu iwọnyi:- Isẹyin, Jos, Ondo, Ilesha, Offa, Ogbomọṣọ, Ṣaki, Kaduna, Ijẹdẹ, Ọyọ, Ile-Ifẹ, Zaria, Gbọngan, Oshogbo, Ọtta, Ilaro Ẹdẹ, Badagry, kọwe si Ulotu 16, Bamgboṣe St, Phone: 21985.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

Rooms & Verandah To Let.

Reliable Bachelor need

Apply to 16, Bamgbose Street Lagos

VOL. IV No. 167 MONDAY JULY 25 — JULY 31 1960 KỌBỌ KAN (1d)

# Awolowo se ileri kiko ile eko giga (University) ni Ipinle IWỌ ORUN

OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ OLORI ẸGBẸ AFẸNIFẸRE, ATI OLORI ẸGBẸ ALATAKO NI ILE IGBIMỌ ASOFIN IJỌBA APAPỌ, TI ṢE ILERI PE TI AWỌN ENIA IPINLẸ IWỌ ORUN BA LE FI DA ẸGBẸ ON PADA NI IBO TI WỌN YIO DI NI ỌJỌ KẸJỌ OṢU KẸJỌ SI ILE IGBIMỌ ASOFIN IPINLẸ IWỌ ORUN, AWỌN YIO KỌ ILE ẸKỌ GIGA ( UNIVERSITIES ) NI AWỌN OLU ILU IPINLẸ IWỌ ORUN, O WA TILẸ YANGAN PE " A O LE AWỌN ẸLOMIRAN BA PẸLU IYANU NLANLA LORI ỌRỌ ILE ẸKỌ GIGA"

Oloye Awolọwọ nsọrọ nibi ipade ipolowo ibo ti ẹgbẹ rẹ ni Igbarra-Oke ni ọjọ Ọjọ'Ru o tun sọ pe "Ti ẹ ba da wa pada sinu ile Igbimọ Aṣofin ti Ipinlẹ Iwọ Orun a o tun bẹrẹ ni ọtun iṣẹ rere ti a bẹrẹ ni ọdun kẹjọ sẹhin, a o tun ṣe kun u fun iyanu yin ati ti ọpọlọpọ enia, a o si mu idẹra wa ba yin ju eyi ti ẹ wa ninu rẹ lọ" O ṣe akajuwe ọrọ ti Ọgbẹni R A. Fani-Kayọde, alaga Igbimọ Eto N.C.N.C ti Ipinlẹ Iwọ Orun sọ pe ẹgbẹ on yio pa owo ori sisan rẹ ti awọn ba gba agbara, gẹgẹbi ọrọ lasan ati isọkuṣọ. Oni ki N.C.N.C. kọkọ ṣe bẹ ni Ipinlẹ Ila Orun nibiti wọn nṣe akoso Ijọba. Oloye Awolọwọ tun ṣe ipade ipolowo ibo ni Apomu, Ikarẹ Ilara, Ile-Ifẹ ati Igara, o si ti ta atare lọ si Ibini, Asaba Ughelly ati gbogbo awọn ilu ti o wa ni Iwọ Orun ti Arin. (Mid-West)

Bi ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nṣe ipolowo ibo, bakanna ni awọn ẹgbẹ Alakukọ nṣe ti wọn. Ọgbẹni R A. Fani Kayọde ni osi nṣe atukọ wọn lọwọ. A gbọ irohin pe Ọlọla Nnamdi Azikiwe koni ba awọn ẹgbẹ re ṣe ipolowọ ibo, nitori iṣẹ ti o nṣe lọwọ nipa ile-ẹkọ giga ti Nsuka, ṣugbọn gbogbo awọn ogunna gbongbo N.C.N.C. yio ya bo ti ti ipolowo ibo ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

## Apeja kan fi Ewon Odun mewa gbara nitori o ji Omo gbe

PORT-HARCOURT:- Ile ẹjọ giga ti fi apẹja kan Rufus Deyor si ẹwọn ọdun mẹwa nitori o ji ọmọ gbe. Ninu idajọ rẹ Adajọ Agba Ọlọla V. A. Savage sọ wipe ọpọlọpọ awọn ọdaran li o nfi ọmọ jiji gbe huwa. ti wọn kosi bikita fun ofin ni ilu wa yi. Mo lero pe eleyi ko ni tun sun wa lọ ba owo ẹru ni siṣe. Ọmọ ti a ka ẹsun rẹ si Deyor lẹsẹ pe o ji gbe ni ọmọbinrin kekere kan Nyone, ti ọjọ or rẹ jẹ ọmọ ọdun mẹjọ ọmọdebinrin yi ni a gbọ wipe, o ngbalẹ ọdẹdẹ alagbatọ ni 176, Bonny Street ni oṣu kẹsan ọdun tokọja, kio to di wipe, ọdaran ajọmọgbe Rufus Deyor wa fi ohun meremere kan tan jade to si ṣe eto ati gbe salọ bamubamu, ṣugbọn o nfi ọkan ọmọde yi balẹ pe on nmu lọ si ile awọn obi rẹ ni, kuro lọdọ alagbatọ.

Ọpẹlọpẹ ara ile awọn ọdọmọbinrin yi, ti o ri wọn nigbati Deyor fẹ wọ mọto ni ibusọ mọto lati gbe ọmọ yi lọ si Ogoni. Bi ko ba si ti Obadiah ara ile wọn ni iba gbe ọmọ yi salọ. Obadiah lo pe Ọlọpa nigbati ọdaran Denyor ko le da lohun ibere ti o nbere lọwọ rẹ pe, ibo ni o ti ri Nyone. Ọlọpa ba mu Deyor lọ si agọ wọn ni wọn ba mu ẹsun ajọmọgbe na lọ si ile ẹjọ giga tihin wọn si ju si ẹwọn ọdun mẹwa ni ọsẹ tokọja.

## Alamojuto Fun Ijoba Geesi ni Ile Naijiria



Ẹniti o wa ninu aworan yi ni Ọgbẹni Ọlọla Antony Head C. B. E. M. P. ẹniti yio ṣe alamojuto fun Ijọba Gẹẹsi ni Orilẹ - ede Naijiria nigbati orilẹ - ede wa ba gba Ominira ni ọjọ kini oṣu Ọktoba ọdun ni.

Olotu Ijọba Gẹẹsi Ọgbẹni Ọlọla Harold Macmillan ninu iwe kan ti o kọ ṣọwọ si Ọlọla Antony Head, sọ wipe pataki ni on mu ipo rẹ, nitoripe ilu ti o tobi ju ni ilẹ Afrika, ti o si jẹ ọrẹ Gẹẹsi gidi ni o ti nlọ ṣiṣẹ. Nitorina ni on fi si adura pe ki Ọlọrun jọki o le ṣe iṣẹ rẹ yanju gidi.

şile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Şile kan pere ni owo rira rẹ, kore egbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nisisiyi, ẹnikẹni le ni "ASPRO" ni ipamọ sọwọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kọlu ọ tabi ẹbi rẹ. Mura silẹ. Ra pakẹti "ASPRO" titun oni şile kan loni!

'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO


## Omobirin kan pe awon Ile-ise re l'ejo

Ile-ẹjọ ti fi ẹjọ ti Omidan Grace Meniru pe awọn ti o ti nşişẹ fun gẹgẹbi ogunfọ ẹrọ teliphonu (telephone operator.) Awọn onişẹ rẹ ni awọn oni beer Iganmu, (Nigeria Breweries Ltd.) Omidan Meniru fẹ gba adọta lerugba meji poun lọwọ awọn onişe yi nitori o sọ pe wọn da on duro lẹnu işẹ lainidi. O ni o di ọdun marun ti on ti şe labẹ wọn. Ẹlẹri mẹta lo si jẹri ninu ẹjọ yi. Ọkan ninu wọn Ọgbẹni Stanley Yentuis ti o jẹ ọga kan nibi işẹ awọn oni beer Iganmu yi, sọ wipe igbati on ma kọkọ mọ Omidan Grace ni igbati awọn fẹ şe ẹkunwo awọn oşişẹ, şugbọn nigbati on wo iwe akọsilẹ rẹ on ri wipe iwa rẹ ko yege.

Ninu ọdun yi, on gbọ wipe o ba oşişẹ kan ja o si ja a jẹ yanayana. Ọgbẹni Yentuis, wa sọ wipe on yan awọn Oluwadi mẹji lati şe iwadi ọrọ na, gẹgẹbi ohun ti Omidan Grace fi ẹnu ara rẹ sọ ni awọn şe da duro. Nigbati agbẹjoro Omidan Grace bi ọkan ninu awọn ẹlẹri pe njẹ bi enia ba ja kilẹ nşe tun? O ni awọn ndaduro ni o wa fun bere lọwọ rẹ kilo şe ti wọn ko fi da Iwọ duro nigbati o ba ẹnikan ja, o dahun o ni gbolohun asọ lasan ni awọn şe awọn ko ja.

Orukọ ẹlẹri yi ni B. E. Bestuis ti o tun jẹ ọga işẹ bakanna. Omidan Joyce Wemba ogunfọ ẹrọ phonu tun jẹri bakanna

## Obirin kan ku lehin adura owuro

CALABAR:— Işẹlẹ nla kan şe ni Ile Obirin Alagba kan Andem Etim, nigbati o ti adura owurọ de, ti o şubu lulẹ ti o si gba ibẹ de Itẹ-Ọlọrun. A gbọ wipe "Obirin alagba yi ni ara rẹ da şaka l'arọ ijọ ti o fi ku yi. A gbọ wipe lẹhin igbati o de lati adura owurọ o bọ si Baluwẹ, o si fẹ wẹ, bi o ti bu omi si ori, ni iku ba de ba a lẹsẹkanna. 15, Egerley-Road ni Obirin yi ngbe.

NI Ibini kẹ onirohin wa kan fi ye wa pe awọn Ọlọpa nwadi ohun ti o pa Ọgbẹni Sunday Ecboma, ẹniti o ku lẹhin igbati o mu ọti kan ti awọn enia kan fun u ni abule Oza ni Akugbe ọpọlọpọ awọn ara abule ni awọn Ọlọpa ti nşe ibere lọwọ wọn.

Ni Aba kẹ awọn Ọlọpa nwadi ohun ti o fa iku ọdọmọkunrin kan ti o fẹran ati ma wọ aşọ daradara, wọn ri oku ọdọmọkunrin yi ti wọn ti ge oku rẹ bi ẹni nşa ẹran ni oju irin Reluwe.

## Ore otito ko si, Ti ika ni o ku

LATI ỌWO AJANPAKO EKO:-

Awọn ọrẹ meji yi ti wa ri ni olu ilu kan. Nwọn jẹ kori-kosun ara wọn, aşọ ẹgbẹ-jọda ni wọn nwọ lojojumọ, bi nwọn ko ri ara wọn, nwọn ko ida şe nkankan. Nwọn fi otitọ inu ba ara wọn lo tobẹ ti ọpọlọpọ enia nfi wọn şe apẹrẹ ọrẹ totọ.

Nigbati o şe aba arin kan nba awọn mejeji şe ọrẹ oju. Ọkunrin yi jẹ ojowu enia, ari-ire-bani-jẹ ati alarekereke. Bi o ti jẹ oloraye to, a ma ba ẹnikọkan ninu awọn ọrẹ re wọnyi lọ si ibi işẹ rẹ, a si ma sọrọ ibajẹ nipa ọrẹ keji Sibẹsibẹ gbogbo ọna ti o ngba lati ba ọrẹ won jẹ ni o nşaki.

Nigbati o şe o ja ogbọn jamba kan. O purọ fun ọrẹ ekini pe ọrẹ ekeji nşe aidara si iyawo a-fẹ-sọna rẹ sibẹ-sibẹ ọrẹ ekini ko gba ọrọ rọ gbọ, o ja si era. O wa di ọjọ kan, aba-rin yi wa sọdọ ọrọ keji, o tan a pe ẹrẹsekiu sọ pe ki o wa pade on ni ni ile iyawo on afẹ ọna ni irọlẹ ọjọ na. O tun sare lọ sọ fun ọrẹ ekini pe o ba di irọlẹ ki o wa lọ wo ọrọ ekeji ni ile iyawo rẹ afẹsọna nigbana ni yio mọ daju pe otitọ ni ọrọ ti on sọ nipa ọrẹ ekeji yi.

Bi ọjọ ti nyẹ ni atari ọrẹ ẹkeji ti nkanju lati pari işẹ rẹ ki o ba le pade ọrẹ ekini ni ibi adehun won Were, bi bi orun ti nfẹ wọ o mu ọna rẹ pọn lọ si ile iyawo ọrẹ ekini.

Iyawo na gba tọwọ tẹsẹ gẹgebi ọre ọkọ rẹ, o şe e ni pẹlẹ, o gbe ijoko fun un. O fẹrẹ ima joko ki ọrẹ ekini ati aba-rin to de. Bi ọrẹ ekini ti ri ọrẹ

WO IYOKU NI OJU EWE KERIN

# OLOFOFO

LATI OWO OMO ADE

Mo ki yin pupo, e ku ipalemo Ominira Oluwa jeki o ba wa ni alafia ati ara lile, ki Oluwa ninu anu Re ko fun wa ni ogbon ti ao fi lo Ominira ni ona eto, ko ma ba di Injra fun wa. E jowo enikeni ti oro ti ose yi ba ta ba ko jowo mase binu Eru kan lo mu ni bu igba. Emi okunrin gidi ti iya fi oja pon ba gbera so ni ojo kan laipe yi ni mo ba dori ko opopo ehin-igbeti nibiti nwon gbe ti nya enia lowo fi kole tabi ra ile ti o ba je osise Ijoba, nitoripe mo nkole kan lowolowo o si wa ni opopo Nomba 5, Custom Street se eji ko mo eni owo ni won bamu mi loba Ogbeni kan ni o se gegebi eto won, o bere eyiti yio bere mo si dahun eyiti o ye ki ndahun, won si ni ki nsanwo asanle mo si se be; mo si kuro nibe ni ojo na, sugbon laipe jojo ni mo ki Telifonu m mole lati bere pe nibo ni won ba eto owo ti mo fe ya de, Arakunrin kan ba dahun pe emi tani o nsoro? ni mo dahun pe emi lagbaja ti o fe ya owo lowo yin ni oruko re si n je lagbaja, ni o ba bere lowo mi pe emi ti se gegebi eto won bi? Mo si dahun pe emi tise gbogbo re ni o ba gbe Telifonu fun enikan, o si dahun pe awon Loya won fe ba mi soro, nibe sa ni won da mi lohun pe ki nwa ni owuro ki agogo mejila osan to lu.

Sugbon gegebi onise asekara emi ko ri aye ni gbogbo owuro ojo ti won ni ki nwa fi owo siwe, sugbon kete ti won si ti bere ise ni osan sa ni emi na ti be wole ni mo ba lo ba won, ni won ba ni ki nlo soke.

Nigbati mo de odo loya won, Akowe re kan joko nigbati mo si ti daruko ara mi ni Akowe na ti mo pe iwe mi ti de owo won, Akowe na fe lo mu faili mi jade, sugbon loya so wipe ase ko ti te won lowo sugbon mo se ibere pe yio to ojo melo ki nto pada wa o si dose meji fun mi, mo si mu suru, se owe kan loso bayi pe ohun ti suru ba se ti ile ni yio gbe, sugbon nigbati mo kuro lodo re ni mo si lo sodo Oyinbo alawo funfun ni mo ba ko ejo ti mo si ro fun ni o ba so fun mi pe ki nma lo na ti o ba di ojo keji ki npada wa ni dede agogo meji abo osan. Enyin onkawe mi ohun ti loya da ose meji fun mi mo gba ni ojo keji loju loya na.

Nje emi Olofofo bere se bayi ni ao se ma lo Ominira wa ti o ba te wa lowo nitoripe laisi awon Oyinbo, ohun kan kole lo dede fun wa.

Eniti o lo ya owo ara ko le de, ko tun lo ya owo lehinna ko tun ma fun nwon l'owo ehin.

## KINI ITUMO ETE KIKUN FUN AWON OBINRIN KARO O JIRE.

Lati ojo ti asa ete kikun yi ti bere ni mo ti nwo ti mo si ti nronu ohun ti o le fa wipe ki a ma sun ikaka ki a ronu wo ki a to dawole ohunkohun se.

Gbogbo wa lo mo daju pe ete kikun kise asa wa rara bikose afara we, nitoto ati ododo pupo ni yio so fun mi wipe emi olofofo kolaju rara, ati wipe emi ko lo silu Oyinbo lati lo fi oju mi ri ohun ti o dara yasi eyiti ko dara, mo fe lati fi ye yin wipe kise gbogbo awon o nlo silu Oyinbo patapata lo nde ti o si nkun ete, melo ni asa awa enia dudu ti awon Oyinbo ko lo silu won, bena ni pupo ninu awon Okunrin ti won lo ko ise Loya tabi Dokita nilu omiran ninu won nigbati won ba ma de nwon a lo gbe Iyawo Oyinbo bo wale, ti o ba si wadi re lo yio so wipe awoe Obi re lo ran on lowon nigbati awon Obi oun ko raye fowo ranse si on mo a tile gba eyi be nitori eniti o gbn ni nigba iponju iyen kuro ni eniti enia le fi owo ta danu.

Enyin a kun ete kise gbogbo asa lo ye ki a ma gba bi eni gba esin, asa ete kikun je asa Asewo to npolowo pe on ko ni oko, nitori eniti o ba oni bawi ti o rii dajudaju iwo yio mo.

Enyin na fi oju inu wo ti eni meji ba nlo ti awon mejeji si je Omobinrin ti okan kun ete ti ekeji ko si kun daju enyin yio ri wipe eyi ti o kun ete ni awon Okunrin yio ma pe laipe jojo eyi ekeji ti ko ti nkun ete na yio beresi kun bakanna ki nwon ba le ma pe on na, nitoripe ete kikun wa fun ipolowo ise Asewo.

O BERE LATI OJU EWE KETA

ekeji inu re ru susu, lai si durogbo'jo tabi gbo labari o ko igbati bo ore e k e j i ati i y a w o re, a koi fi ni sesin bi ojo aya-oni ri,

Abarin ti o ro pe on se nkan gumo sare lo pe awon aladugbo lati wa woran ohun ti ore ekeji se si ore ekini. Nigbati awon aladugbo fi lakaye gbe oro na yewo, nwon sipe fun ore ekeji pe ki o fi iya para ki o fi ija f' Olorun ja ki o fi owo l'eran Ore ekeji dahun pe on ko binu nitoripe o daju pe laipe jojo ore ekini yio mo pe " Kijipa ki ise awo.

WO IYOKU NI OJU EWE KARUN

## Elewon wo Gidigbo ni Kotu

Ile ejo Alkali agba ni Ilorin di ile gidigbo nigbati odaran kan ti won ju si ewon osu mesan gba Agbejoro Ijoba Ibile leti, ti o si bawo iya ija odaran yi ni: Jimoh Alaro eniti o nsewon osu mefa lowo fun biba Obinrin sun ni ipa ni won tun ju si ewon fun iru ese kanna. Lesekese ti won ti da ejo fun u ni Jimoh ti bere si mu Alikali bu, nigbati awon Olopa ti o wa lenu ise ni ki o dake nise ni o mu Agbejoro gba leti, ti o si wo iya ija pelu awon Olopa ti o ku.

## Omo Geesi keta fun ere Olympic ti odun yi (1960)




Enitiṣo wa ninu aworan yi ni B. W. Kent - Smith, eniti o sa ere, ti o si yege ni ilu Fifun Londonu (White City London) ninu ere ije ti Geesi ati Italy se ni Londonu lenu lolo yi. Ninu ere ese egbarun ti won sa, B. W. Kent-Smith fi iseju meta gedegbe sare, eleyi si je ki o le wa ninu awon ti yio sare ije ni ti ere agbaiye, Olympic ti odun ni. Geesi lo bori ere ije na ti won se pelu Italy,

ADVERT. NO. 91

## FIFI ORUKO SILE FUN AWON OMODE TI YIO BERE ILE IWE L'ODUN TI MBO. 1961

Alamojuto eto iṣẹ ẹkọ fun Ijọba Apapọ Naijiria, ọlọla Aja Nwachuku, ti fun ẹniti ndele de ọga ile iṣẹ Ijọba ti nṣe eto l'ori ẹkọ, Ọgbẹni E. J. Moses, ni aṣẹ lati bẹrẹ si gba orukọ awọn ọmọde ti yio ṣẹṣẹ bẹrẹ ile iwe l'Eko l'odun ti mbọ silẹ, gẹgẹ bi ofin Ijọba ti wọn ṣe ni ọdun 1957.

2 Nwọn yio bẹrẹ si gba orukọ silẹ lati agogo mẹjọ si agogo mẹwa l'arọ ati agogo mẹrin si mẹfa ni aṣalẹ lati ọjọ kejilelogun oṣu kẹjọ (August) ọdun yi titi di ọjọ kẹrinlelogun oṣu (August). Ọna metadinlogorin na ati awọn ile iwe ti Ijọba lọwọ si yio jade ninu ikede ti Ijọba yio ṣe ninu iwe irohin nigbati o ba ku ọsẹ kan ki nwọn bẹrẹ si fi orukọ awọn ọmọ ọwọ na silẹ

3 L'ọjọ ti a wi wọnyi, ki olukuluku obi mu ọmọ rẹ ti o ba bi ni ọdun 1955 pẹlu iwe ọjọ ibi rẹ lọ si ibi ti nwọn ba ti gba orukọ silẹ fun ile iwe ti o fẹ ki ọmọ on lọ.

4 Ko ni si aye fun ọmọkọmọ ti ko ba fi orukọ silẹ ni asiko ti a wi yi lati bẹrẹ ile iwe ni ibẹrẹ ọdun ti mbọ, 1961, afi bi o ba jẹ pe awọn obi rẹ le fi han gbangba pe EKO ni wọn ngbe ni ibẹrẹ ọdun 1960, ṣugbọn awọn ko sisi ni EKO mọ l'asiko ti nwọn nfi omọ silẹ.

## Awon egbe omo ogun Naijiria



Awọn ọmọ ẹgbẹ ogun Naijiria meji Sgt Mayor Nathan Dilli (osi) ati Sgt Mayor Amadu Katshina nba Stg. George Higgins ti ilu Oyinbo sọrọ lori tito ti wọn to niwaju Ọba-binrin ti ilu Gẹẹsi lẹnu lọlọ yi Wọn gbayi wọn gba ẹyẹ ninu tito na.

Gbogbo awọn alaṣẹ Olotu ati awọn alakoso ilẹ Naijiria ni o lọ wo wọn nibi ẹyẹ tito na ni Afin Buckingham. Ọba-binrin si fi iyin fun wọn.

## Ore otito ko si, Ti ika ni o ku

O BẸRẸ LATI OJU EWE KẸRIN

Awọn enia ti nwọn mọ bi awọn mejeji na ti jẹ ọrẹ timọ-timọ ri, dide lati ṣe atunṣe ọrọ na, nwọn gba awọn ọrẹ mejeji na ni iyanju pe ki nwọn fi egun otolo to ọrọ na lati ba d'oju ti ẹlegan. Ṣugbọn ọrẹ ekeji fi ada kọri pe ọrẹ ti on ati ọrẹ ekini ti ja ko si le ṣe iso mọ. Agbara kaka ni awọn enia fi yi i lọkan pada nipa awi iyanu nwọn nitori Awi ma-yẹun ni ọrẹ ekeji jẹ. Bi ko ba si ti awọn onilaja na ni boya nibẹ papa awọn ọrẹ meji iba fi pẹki ko pẹki ( fi ija pẹta) ni ọjọ na. Awọn onilaja na ti a le pe ni Ma-jẹ-o-bajẹ yanju awọ na, awọn ọrẹ mejeji si tun nba ọrẹ wọn lọ bi ti iṣaju.

Ni gbogbo akoko ija yi, abarin nlọ, o nbọ o nṣe boro-borọn, o nfarahan bi ẹnipe on jẹ ọkan pataki ninu awọn onilaja larin awọn ọrẹ meji na.

Ko p'ọjọ ko p'oṣu lẹhin eyi birimọ yi Abarin ji oruka wura kan ni ile bọkini kan, nigbati o ṣe akiyesi pe awo fẹ ya o fi oruka na fun ọrẹ ekini ki o fi pamọ fun on. O yara sare lọ si ọdọ ẹniti o ni oruka na, o ni "Bi o ba le fun mi ni ẹbun ti o jọju, emi yio fi ọna han ọ lati ri oruka wura rẹ" Bọkini na tẹ ifẹ Abarin lọrun. Abarin mu Bọkini na wa si ile ọrẹ ekini. Bi wọn si ti wọle Abarin sọ fun ọrẹ ekini pe "ọkunrin yi nfẹ ra oruka wura kan, jọwọ mu ti ọwọ rẹ fun un ki o yẹ wo boya iru eyi ti o fẹ ra ni."

Ọrẹ ekini mu u fun alejo na, bi o si ti yẹ ẹ wo ti o ri wipe oruka on ni o gba ọrẹ ekini l'eti lẹmẹta o ke ibosi ole le e lori, ọlọpa de. o si mu u lọ. Bi ọrẹ ekeji ti gbọ irohin na odu barabara lọ si ọgba ọlọpa, o ba ọrẹ ni dide, nwọn si nmura ati ṣe ẹjọ fun un ni ile. Ọrẹ yi duro fun un o mu bọ wa si ile titi ọjọ ẹjọ na fi ko. Nigbati ọjọ ẹjọ pe adajọ da ẹwọn gbọrọgbọrọ tabi owo pupọ fun ọrẹ ekini, ṣugbọn kaka ki o lọ si ẹwọn, ọrẹ ekeji sare wa si arin ilu lati wa owo lọna-kọna o si san owo ti adajọ bu fun ọrẹ ekini lati san, bẹni o yọ ọrẹ yi patapata ninu lasigbo tabi rogbodiyan na. Ni gbogbo akoko ẹjọ na abarin ko yọju rara.

Nigbati wọn de ile, ti oju ọrẹ ekini walẹ, nwọn wo ara wọn loju titi, ọrẹ keji wipe "Yegede, ko tan ni idi rẹ na, oju rẹ ko ha a ja nisisiyi, o ko ha mọ nisisiyi pe "Kijipa ki ṣe awọ. Ọrẹ ekini tnmba fun ọrẹ ekeji, o dupẹ lọwọ rẹ, o bẹ ẹ ki o ṣe aforiji iṣiṣe on lati ẹhin wa. O wa bẹrẹ si irohin bi Abarin ti ṣe da ija silẹ larin wọn nijelo, ati bi o ti ṣe ta jamba fun on nipa oruka wura na. Lati ọjọ na lọ awọn mejeji jọ mulẹ nwọn si fi ọgẹrẹ bura pe, awọn ki yio da ara wọn lai nwọn pinu lati ga fun Abarin, ẹniti itiju ko tilẹ jẹ ki o tun sunmọ sakani wọn mọ.

Abarin, a bọrẹ jẹ. Eku wẹrẹwẹrẹ da ọkẹ lu Afi inu ya 'na fi ẹhin ya orun A-dija silẹ takete.

## Aye si sile fun Enyin omo Yoruba kakiri Ilu karo-o-jire!

Lati Ọwọ:- OMIDAN JANET.

Lati ọjọ ti ẹgbẹ N.P.C. ti wọle ni ile Igbimọ Apapọ Naijiria gbogbo ẹnyin ọmọ karọ o jire ti bẹrẹsi gburo orişirişi ohun abami, ti a ba ri ẹnikẹni ti ohun ti mo nsọ yi ba jẹ ajoji si ki o gbidanwo rẹ wo ki o jẹ kin ngbọ. Nigbati ẹgbẹ mejeji na ti bẹrẹsi ṣe Ijọba a ko ri ohun iṣiri kankan rara diẹ ninu ọrọ ti mo nsọ yi le ye gbogbo ẹnikẹni ti o şişẹ owọ tabi iṣẹ kọntirakitọ yio mọ daju daju ti Hausa ko ba ri iṣẹ gba iwọ ọmọ karọ-o-jire kole ri ohunkohun gba, bẹna ni ile ẹkọ ti awọn ọmọ Hausa ko ba ti ri ile ẹkọ wọ iwọ ọmọ karọ-jire kole ri ọna wọle ẹkọ.

Nitori idi eyi mo kesi gbogbo ẹnyin ọ m ọ Yoruba ki ẹ jọwọ di amure yin giri-giri fun I D I B O ti Iwọ Orun ti nwọn yio ṣe ni ọjọ kẹjọ oşu kẹjọ ọdun yi, nisisiyi ẹgbẹ N.C.N.C. yio ma kegbe pe yin wipe awọn ki yio gba owo Ori mọ IRỌ funfun ni eyi fun ẹnikẹni ti o ba ni oye nitori ko si ilu ti o le da duro laiko san owo ti ilu na le ni eto ti o ye koro, ida-keji ẹwẹ, mo fẹ ki ẹ mọ daju wipe ẹgbẹ N.C.N.C. ko si le da duro fun ra ra nwọn, bikoşepe wọn pe ọ m ọ Iya wọn şikeji wọn eyi ni ẹ g b ẹ N.P.C. nitorina ẹ jọwọ ẹnyin ọmọ Iya mi mo fi Alajọbi Karọ-o-jire bẹ yin ẹ ma ṣe gbagbe ọjọ na lati lọ di'bo fun ẹgbẹ 'ỌLỌPẸ' fun isowọ-pọ awa ọmọ Yoruba. O di-gbamiran o!

# Itan igbesi aiye Alaiyeluwa Alafin atijo Sango.

Lati ọwọ J. O SHOYINKA MUSHIN

Olotu jọwọ ẹba mi laye lati sọ itan Igbesi aiye Ṣango ẹniti o bi, Ogun ti o ja ati bi o ti ṣe di Ọba. Ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ-karọ-o-jire ni ko mọ pe Alafin Ọyọ atijọ ni Ṣango nṣe, Irunmalẹ ni wọn npe e.

BABA ṢANGO

Ọranmiyan lo bi Ṣango Olukoso, nigbati Ọranmiyan ba Elenpe (Ọba Tapa) ṣigun ti awọn ọta rẹ ti o si ṣẹgun wọn, Elenpe ronu ohun ti on yio fi ta lọrẹ ko ri, ni o ba mu Arẹmọ-binrin rẹ, o si fifun Ọranyan pe ki o ma fi ṣe iyawo. Orukọ arẹmọbinrin rẹ na a ma jẹ Ogolu Torosi, ọmọbinrin yi ni o si bi Ṣango fun Ọranyan idi rẹ ni afi npe Ṣango ni ọmọ Tapa.

Nigbati oyun ṣango wa ninu ni O r a n m i yan ti fi Ogbolu Torosi ti baba rẹ Elenpe, o si gbe ogun lọ ti ilẹ Ibariba. Nigbati Ọranmiyan yio fi ti ogun de, iyawo rẹ Ogbolu ti ku ni ọjọ kanṣoṣo na ti o bi ọmọ, gẹgẹbi aṣa awọn Tapa, nwọn ni ha! iru egbere ọmọ wo ni eleyi? Ọmọ gbẹmi gbẹmi, laisianiani ewele asawọ ni eleyi, wọn gbe gidi ganranur., wọn sọnu sinu igbo, ki o ba le lalaṣe iku, ṣugbọn abo ẹkun kan ti o ṣẹṣẹ bimọ, ko jinna si tosi ibẹ, eyiti iba fi pa a jẹ, o bẹrẹsi fun on ati awọn ọmọ tirẹ lọmu papọ, bi ọmọ yi ti ndagba ni awọn ọmọ ẹkun papa ngberu. Nigbati o ya Ọranmiyan ti ogun de, o gbọ nipa ti iku iyawo rẹ, ibanujẹ dori rẹ kodo, ṣugbọn gẹgẹbi jagunjagun enia ko pẹ ti o fi ṣe ara giri, o fiinu finlẹ titi, o wa bere ibiti ọmọ ti o gbe bi wa, o si rẹni sapejuwe fun pe ẹkun ni o ntọju ọmọ rẹ, eyiti iba fi ba ẹkun yi ki o to gbe ọmọ rẹ, on papa ṣe ẹkun yi lore nipa pipa awọn abọra fun, ni kukuru o gbe ọmọ rẹ wa sile. Ọpọlọpọ ko mọ idi rẹ ti a fi npe Ṣango ni ọmọ ẹkun, idi rẹ ni eyi o, ẹkun ni o fun ni ọmu mu dagba o.

NIGBATI ỌRANMIYAN DELE O SỌMỌ NA LORUKỌ

Gbara ti Ọranmiyan ti gbe de ọdọ baba rẹ Odudua, ni o ti sọ ni orukọ Ṣango, ede legibiti lailai ni o fi sọ ọmọ yi lorukọ (Itumọ rẹ ni alagbara) orukọ ni ma ro enia, nigbati Ṣango dagba tan o di alagbara ati ologun bi ti baba rẹ Ṣango ni o gbapo ẹgbọn rẹ Dada nigbati awọn ara Ọyọ rọ loye nitoripe ko jafara ati pe o si gba lati ma sin ori olori.

ṢANGO JE ALAFIN

Ṣango jẹ Alafin Ọyọ, gbara ti o ti de ori oye ni o ti gbogun ti Olowu Ogun, o si ṣẹgun rẹ, eyiti mu ki awọn Yoruba di ominira papa julọ Ọyọ. Lati igba yi lọ ni awọn Yoruba si ti ma pa lowe pe "Dada ko le ja ṣugbọn o ni aburo to gboju". Lẹhin ti o jagun ti o m'olu tan, o tun gbogun ti awọn Ara Ibadan Akọkọ, o si ko wọn, ẹsun ti o ka si wọn lọrun ni pe wọn ba AWO EGUN jẹ. Iwa ipanle rẹ pọ tobẹ gẹẹ ti o fi jẹwipe o bẹrẹsi mi ilu lara.

Gẹgẹbi ẹ ti mọ pe ilu ki wa ki o ma ni akọni enia awọn meji ti o jẹ akọni wa ni Ilu Ọyọ ni igba na Orukọ ekini njẹ Gbọnka Ẹbiri ati Timi Agbale Ọlọfa Ina, wọn lagbara wọn logun eyi mu ki Sango funrara rẹ wọn. Lọjọ kan Ṣango pe awọn ẹmẹwa rẹ jọ, o ni, on ti ngbiro Timi Agbale Ọlọfa Ina ati Gbọnka Ẹbiri ti pẹ, pe alagbara enia ni awọn mẹjeji iṣe, atipe on fẹ mọ ẹniti o lagbara julọ ninu awọn mejeji, o ran ikọ si wọn pe ki wọn fi oju kan on. Nigbati wọn de Afin, Ṣango ki nwọn, o yin wọn o ni ohun ti on pe wọn si ko lọ tiantian, on fẹ mọ ẹniti o lagbara julọ ninu awọn mejeji atipe ti o ba di ọjọ meji loni ki nwọn pade ara wọn ni ọja Akẹsan lati wa fi agbara han ara wọn.

Ọjọ pe, gbogbo ilu pe lọ biba Gbọnka Ẹbiri ati Timi Agbale Ọlọfa Ina pade, wọn taketo si ara wọn olukuluku bẹrẹsi pọfọ, ni kukuru Gbọnka Ẹbiri ṣẹgun Timi. O pe gbogbo ilu jọ lẹkeji o ni mo ti ṣẹgun ọta mi, ki ẹ to le mọ pe agbara kekere kọ ni mo ni.

KO ITI PARI, O DI ỌSẸ TOMBỌ.

AWỌN AGỌ IPINLẸ

EYE IFIHAN NAIJIRIA

VICTORIA ISLAND

LAGOS OCTOBER 1st--22nd

Be ile eye ifihan na wo ki o si ri...

Awọn Ijọba Ipinlẹ kọọkan yio ni ago tiwọn ninu Eye Ifihan Naijiria ti wọn yio si l'Eko ni ọ'o Idominira.

- ILA-ORUN yio fihan bi ẹkọ rere ti nṣe iranlọwọ lati gbe iṣẹ-ọwọ ati iṣẹ-agbẹ ga soke dada.
- ARIWA yio ṣe apẹrẹ bi o ti ṣe nyanju awọn isoro ti o wa ninu iṣẹ-agbẹ, ilera, ẹkọ ati ipese omi.
- IWỌ-ORUN ti yan ipilẹ "Ilọsiwaju" yio si ṣe alaye bi iṣẹ-owo rẹ ti ṣe ni idagbasoke titi di ọjọ oni ati bi o ti ri akoko ti o mbọ si pẹlu itẹnumọ lori eto idagbasoke ọdunmarun Ipinlẹ na.

Awọn ohun-ifihan ti o fanimọra ti a o fi han ni:

- Ile akojọ-iwe ti a le ṣi nipopada; apejuwe aṣọ AKWETE ti Ila-Orun fun Ọlọlajulọ Alaiyeluwa Elizabeth keji Ọbabirin Gẹẹsi.
- Awọn Ọmọ-ogun-Ẹṣọ awọn Ọba Ipinlẹ Ariwa ti o gun ẹṣin. Iwe apejuwe Ilẹ-Ariwa ti o gborin.
- Ile-iṣẹ Ẹrọ Redio Alaworan; aworan apẹrẹ oko Co-operative lati Iwọ-Orun.



AWỌN IJOBA IPINLẸ NAIJIRIA LONI ATI TI EHIN-OLA